# O TUN NPADA BỌ

Tani ẹniti O npada bọ naa? "Jesu naa yi, ti a gba soke ọrun kuro lọwọ nyin, yi O pada bẹẹ gẹgẹ bi ẹ ti ri I ti O nlọ si ọrun" (Ise Aposteli 1:11). Awọn angeli meji ni o sọ awọn ọrọ wọnyi fun awọn ọmọ-ẹhin ti ọkan wọn gbọgbẹ ti o si kun fun ibanujẹ bi nwọn ti gboju soke ti nwọn si nwo awọsanma ti o gba Oluwa ati Olugbala wọn ti nwọn fẹ julọ kuro ni oju wọn.

Jesu Kristi paapa se ileri nigbati O si wa lori ilẹ aiye wipe: "Emi nlọ ipese aye silẹ fun nyin . . . Emi yio tun pada wa, Emi yio si gba nyin si ọdọ ara Mi" (Johanu 14:2, 3). Ni nkan bi ọgọta ọdun lẹhin eyi, Kristi tun fun wa ni idaniloju ipadabọ Rẹ lati ọrun wa nigbati O wipe: "Nitootọ, Emi nbọ kankan" (Ifihan 22:20).

Ipadabọ Jesu Kristi lẹẹkeji jẹ ẹkọ ti o jẹ otitọ ti o si daniloju ti a si fi idi rẹ mulẹ sinsin ninu gbogbo iwe ti o wa ninu Bibeli. "Ọlọrun ki iseke," "Ọrun ati aiye yio kọja lọ, sugbọn awọn ọrọ Mi ki yio kọja lọ" (Titu 1:2; Matteu 24:35). Gbogbo ọrọ Ọlọrun ni o nilati ni imusẹ.

Aposteli Peteru ninu Episteli rẹ sọ wipe,

ni igba ikẹhin awọn ẹlegan yio de ti nwọn yio si wipe; "Nibo ni ileri wiwa Rẹ gbe wa? lati igbati awọn baba ti sun (ku) ohun gbogbo nlọ bi nwọn ti wa ri lati igba ọjọ iwa." Sugbọn ọrọ Ọlọrun tẹsiwaju lati sọ wipe: "Oluwa ko fi ileri Rẹ jafara, bi awọn ẹlomiran iti ka ijafara; sugbọn O nmu suuru fun nyin, nitori ko fẹ ki ẹnikẹni ki o segbe, bikose ki gbogbo enia ki o wa si ironupiwada" (2 Peteru 3:4, 9).

Oluwa nduro de ọ wipe ki o ronupiwada awọn ẹsẹ rẹ loni, ki o si gba On gẹgẹbi Olugbala rẹ. "Nitorinaa ni Oluwa yio duro, ki o le se oore fun nyin" (Isaiah 30:18). Sugbọn akoko nbọ nigbati "Eni naa ti O mbọ yio de, ki yio si jafara" nigbanaa ni ilẹkun igbala yio ti titi lai (Heberu 10:37).

Lati inu ọrọ Ọlorun ni a ti mọ wipe bibọ Oluwa yio pin si ipa meji. Ni akọkọ On yio farahan ni awọsanma, fun awọn kristiani tootọ ti o ti nduro de bibọ Rẹ, lẹhin naa ni yio sọkalẹ si ori ilẹ aiye yi gẹgẹbi Ọba ati Onidajọ.

Aposteli Paulu wipe: "Oluwa tikara Rẹ yio sọkalẹ lati ọrun wa ti On ti ariwo pẹlu ohun olori awọn angẹli, ati pẹlu ipe Ọlọrun; awọn oku ninu Kristi ni yio si kọ jinde: nigbanaa li a o si gba awa ti o si ku lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanna, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẹeli awa o si maa wa titi lai lọdọ Oluwa" (1 Tessalonika 4:17-17).

Eleyi le sẹlẹ nigbakuugba. Jesu Kristi funra Rẹ wipe awa ko le mọ "ọjọ tabi akoko" ti On yio de (Matteu 25:13). Ohun gbogbo yio maa lọ gẹgẹbi o ti nlọ naa ni, nigbanaa lojiji, ọpọlọpọ awọn enia yio 'sonu, awọn ti yio sọnu wọnyi ni awọn kristiani tooto, nwọn yio si "wa titi lai lọdọ Oluwa" ni ọrun.

Jọwọ ara rẹ fun Jesu Kristi ki O to pada de, bi bẹẹkọ, On yio fi ọ silẹ sori ilẹ aiye lati dojukọ awọn idajọ gbigbona ti o si banilẹru gidigidi, eyiti iwe ti o kẹhin ninu Bibeli sọ nipa rẹ fun wa. (Wo Ifihan ori 6 titi de ori 19) Jesu sọ nipa ọjọ wọnni wipe: "Nigbanaa ni ipọnju nla yio wa, iru eyiti ko si lati igba ibẹrẹ ọjọ iwa titi di isisiyi, bẹẹko, iru rẹ ki yio si si" (Matteu 24:21).

Lẹhin ipọnju nla ti a ko ri iru rẹ ri yi (ọdun meje gbako ni yio gba gẹgẹbi Danięli 9:24-27 ti wi) Jesu Kristi yio sọkalẹ sori ilẹ aiye ninu gbogbo ogo Rẹ, pẹlu gbogbo awọn angẹli Ọlọrun ati awọn enia mimọ, On yio si tẹ itẹ idajọ Rẹ sori ilẹ aiye: "niwaju Rẹ li a o si ko gbogbo orilẹ-ede jọ: yio si ya wọn sọtọ kuro ninu ara wọn, gẹgẹbi olusọ-agutan iti ya agutan rẹ kuro ninu ewurẹ" (Matteu 25:31, 32). On yio si se idajọ ododo ti ko si se yipada fun gbogbo awọn ti ko gba A ni Oluwa ati Olugbala (wo Ifihan 19:11-21). Nigbanaa ni yio fi idi Ijọba Rẹ kalẹ, On yio si maa jọba gẹgẹbi Olori giga julọ lori gbogbo ilẹ aiye.

Akoko bibọ Oluwa nsunmọ tosi. "Ikaanu awọn orilẹ-ede, pẹlu aifọkanbalẹ," "ogun ati irọkẹkẹ ogun," "iyan, ajakalẹ arun, isẹlẹ nlanla." "ọkan enia ti ndaku pẹlu ẹru, ati nitori ifojusọna si awọn nkan ti o nbọ wa sẹlẹ

si aiye yi," ati ikorira orilẹ-ede Israeli ti o npọ sii, ni diẹ ninu awọn ami ti Bibeli sọ fun wa wipe yio sẹlẹ ni igba bibọ Rẹ (Matteu 24: 3-9, ati Luku 21:25-28). Njẹ awa naa ko nse ẹlẹri ibẹrẹ awọn nkan wọnyi loni bi? Iro ọpọ ẹfuufu lile npọ sii dajudaju.

"Sa asala fun ẹmi rẹ!" "Sa fun ibinu ti o nbọ!" eyi ni ikilọ Ọlọrun fun ọ.

Jesu Kristi Olubukun julọ yi kanna, ti O wa si aiye ni nkan bi ẹgbẹrun ọdun meji (2,000) sẹhin lati ku fun ẹlẹsẹ, On kanna ni iwọ ti dẹsẹ si. O si wa nrọ ọ loni wipe ki o wa, ki o si jẹ wo ẹsẹ rẹ fun On, ki o si kọ awọn ẹsẹ naa silẹ; On yio si fi tayọtayọ gba ọ, yio si dariji ọ, yio si wẹ ọ, iwọ yio si fun ju yinyin (sno) lọ. "Ẹjẹ Jesu Kristi Ọmọ Rẹ (Ọlọrun) si nwẹ wa nu kuro ninu aisododo gbogbo" (1 Johanu 1:7). Ọna kansoso ti o le gba mu ẹsẹ rẹ kuro niyi.

Ọlọrun fẹran rẹ, O si nwạ ọ. O nfẹ lati jẹ Olugbala rẹ. Sugbọn bi iwọ ba kọ lati gba A, On yi kanna ni yio tun jẹ Onidajọ rẹ, nigbati akoko ba to. Wa si ọdọ Rẹ nisisiyi, iwọ yio si se tan lati pade Rẹ nigbati O ba pada de, iwọ yio si ri ibukun aiyeraiye gba lọfẹ.

**Word Of Truth**, P.O. Box 1126, Kaduna, Nigeria